**Ikede**

Awe Ikede yi f u n gbogbo Enyin Okawe wa ati awoju wa wipe, Eni keni ti owo ba seku pe owo re ki o tete fi ranse nitori gbogbo ohun elo ti a fi nsowe iroyin lo ti gbe owo leri. Enikeni ti ko ba fi tire ranse ... da iwe re duro ... agbara lati gbe owo wa ni owo re. Oloba.

ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI-L'EJO

## Ode To Sun Eja Gbe Iwo Re Lo

Ode ... o si ... iwo re ... lo ... emi.

VOL. VII No. 403 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA FEBRUARY 19 1955. IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI

# Bi Olubadan Ba Ku Tani Yio Joye?

**Eko** Ohun ti o ba jo ohun ni a fi nwe ara won. Ododo oro ni. Enyin okawe wa, bi e ba se akiyesi nipa ohun ti ero gbohun-gbohun (Radio) mbere lojojumo wipe Bi Olubadan ba ku, tani yio joye?.

E ko miye lode wipe, ero na ri tee ki o to ma wi lemo-lemo. Yoruba si npowe wipe, Bi Alagbede ba nlu irin timo-timo, o ye ki a mo wipe nkan mbe nidi re. Enyin okawe wa, oro na se tabi ko se.

Orin li o nsiwaju ote. Samo Samo ero na ri ohun ti o mbo wa sele Ki o to ma ke lemo-lemo pe, bi Olubadan b ku tani yio joye, enikan ko si kiyesi ara nipa ibere ero na.

Ododo oro na jale laipe yi nigbati Igbintade Olubadan salaisi ni ede koyede wa be sile larin tani yio je oye. Awon Ijoye ati awon Afobaje panupo yan Balogun Ibadan lati joye na. Lehina ni awon apakan enia tun lo yan Osi Olubadan lati wa je oye na.

Enyin okawe wa, nje asotele ero Radio yi ko ba se baun?. Bi Olubadan ba ku tani yio joye.

## Adegoke Adelabu Pekelemesi



**Ibadan** Eniti a nwo y ni Ogbeni Adegoke Adelabu ti o nse okan ninu awon asoju Ibadan larin awon Ministers.

On ni okan ninu awon alatilehin fun Akinyo ti o mba I. B. Akinyele du oye Olubadan. Ajele agba ti pe, o si ti se ikilo fun ati awon isongbe re wipe penke ko gbodo mi, kulu ko gbodo so ni Ibadan.

## Ijoba Fi Ase Si Owo Lebira Sile Merin Lojumo

**Eko** Ninu osu Oct 1954 ni Ijoba Iwo-Orun so owo ise ojojumo awon Lebira di sile marun-marun gegebi leri ti nwon ti se f u gbogbo awon osise wipe, bi nwon ba bo si ori aga ijoba a w o n yio da gbogbo awon osise ti o mbe ni agbegbe Iwo Orun ni ola. Sugbon nigbati idera ekunwo na ma fi de ko de odo awon ti o nsise ni Eko nitoripe gedegbe ni Eko wa Laseko na ati ile Ibo ati ile ...

Nigbati oro ri bayi, awon osise ilu Eko, ile I b o ati ile Hausa fi gbe ta w i p e kinni obo ti se ori ti Inaki kose. Bi ijoba Iwo-Orun ba nfun osise ni sile marun, eto ni ki awon na paapa gba ekunwo.

Eyi lo mu ijoba l a t i yan awon enia kan lati lo se iwadi iye ti o to ki awon lebira ma gba. Jake. j a d o Be Nigeria. Bayi ni nwon si yanri re si Awon ti o nsise lebira nilu Eko yio ma gba sile merin lojumo Awon to mbe ni agbegbe Ikeja yio ma gba sile meta ati kobo marun lojumo. Ni Burutu ati Forcados, nwon o ma gba sile meta lojumo. e y i y i ni abo gedegbe ni eko wa.

## Adajo Ko Lati Gbo Ejo Koburu To Wo Ewu Buba

**Eko** Koburu Olopa kan li o wo ewu buba wa si kotu lati rojo. Nigbati o bo sinu apoti lati rojo, adajo so wipe, bi o ba je wipe olopa ni eniti o fe rojo yi, emi ko ni eti fi sere.

Agbejoro ijoba si dahun wipe ki adajo mase binu nitori bi o tile je wipe olopa ni okunrin na ko gbo tele wipe ko dara lati fi ewu buba wa jeri ni kotu.

Laiti gbo ase lenu adajo, koburu na tun gbe iwe Bibeli o si nfe bere si bura. Ibe ni Adajo tun so fun Agbejoro wipe okunrin o l o p a ti e mu wa ti o si wo ewu wa si waju mi lati wa jeri emi ko ni fi eti si oro re, bi ko ba si afojudi o fere le san bante wa siwaju mi lati wajeri

Nigbana ni Agbejoro oba rase ki olopa na kuro n i n u apotieri, o si lo wo ewu agbada nigbana ni adajo to wa gbo ti enure.

## Awon Ero Man Of War Bay

**Ilesha** Ninu awon omo akeko ti a yan lati lo se idaraya ni Man of War Bay nile Kameru, awon omo akeko mefa l a yan lati ilu Ilesha ti yio ba won lo.

Oruko awon ti a yan lati Ilesha niwonyi. (1) Babafemi Farodoye (2) Olufemi Sarumi (3) Babasola Popoola (4) Ishmael Onigbogi (5) Edward Adesoyin (6) ati Ladimeji Osungbure.

## Ogbeni Osungbure Di soju Fun Awon Ijoye

**Ilesha** Ogbeni Ladimeji Osungbure n i a w o n ara Ilesha ti fi ara mo w i p e ki o j asoju fun Ogbeni won ninu igbimo awon Ijoye Ilesa ati ... ni Ogbeni Itisin fara mo be.

Tele-tele Ogbeni Ladimeji yi je akowe fun egbe Afenifere n i l u Ilesha, o si je eniti o ni akinkanju jojo o si tun ni ife ilu re li okan.

## Adajo So Wipe On Ko Gbodo Gburo Ija

**Ibadan** Li ojo Jimo ti ana yi, 18th Feb ni Balogun Ibadan Ogbeni I. B. Akinyele yio wuye gegebi Olubadan ilu Ibadan ti nwon o si ja ewe oye le lori.

Sugbon irohin ti gbojikan kakiri wipe die ninu awon agba Ijoye ti mura sile de ojo na lati da reke-reke sile.

Nitorina Adajo ranse pe awon ogbeni nwonyi Bello Akinyo, S. Sogbolade, S. O. Aderogba, S. Aminu, ati Yesufu Kobiowu

O se ikilo fun won pe, ki eku ile wi fun ti oko, won fe jawe oye le Akinyele lori ojo ko gbodo su, pere ko gbodo so, bi ija kan ba sele, awon ni yio fi ori fa.

## Ejo Bale Modakeke Fe Bere

**Ife** Bale ilu Modakeke pelu Babalowo kan ati iranse Bale awon eniti Olopa fi sun esun wipe, awon li eniti o pa omo ilewe kan ti o nti Ilefe lo kawe ni ilu Modakeke ti a npe ni Fatayi Amao, omo odun merinla.

Awon eniti a niyi ti lo gba Loya H. O. Davies, nwon si dahun wipe awon ko jebi.

Davies so fun adajo wipe nisisiyi ti on fe bere ejo eri ti Babalawo ati iranse Bale ti je ki adajo mase gbagbe. Adajo si dahun pe, nwon ko mu won nipa lati se.

# ELETI QFE

A-NIU-WỌN KO SE WI L'EIQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS — CABLES & TELEGRAMS
76 Kosoko Street, Lagos — "ETI-QFE LAGOS"
P. O. Box 467 — Phone 23370

VOL. VII NO. 403 LAGOS SATURDAY FEB. 19 1955.


## Qte Ibadan Ka Ma Ri i Lodun

Nigbi lailai nile Yoruba bi awon onilu ba nsakiyesi wipe ote ni awo ilu kan, nwon o ma fi ote ti ilu Ibadan si won leti nipa lilu ilu Gangan bayi wipe, ote Ibadan ka ma ri lo dun.

Gbolohun yi ni a fi jomitoro oro sinu iwe Irohin wa lose yi, lati fi si awon omo Ibadan leti iru ise buruku ti ote ti da sile ninu won nigba lailai, ki nwon le ronu, ki nwon si yera kuro nibi tembelekun ti o nfe gberu lorin won yi nitori ki nwon ma ba sabamo.

Nitoripe eti wa kun fun irohin okan ko jo okan wipe apakan awon ara nfe da ote sile lori oye Olubadan ti a sese je. Ko si nse oni yi ni nwon ti nje oye yi.

Oye Bale ni nwon ti nje ri, ki Alafin to da won li ola lati ma je Are ti o tobi ju Bale lo eniti o koko je oye na ni Are Lafosa. Lehin na ni Alafin tun dawon lola lati maje oye ti o tobi ju Are lo eyi ni oye Bashorun, awon ti o si je oye na ni Basorun Osungbekun ati Basorun Apanpa.

Ngehin Ibadan di Ominira kuro labe asingba Oyo ni nwon bere si joye Olubadan. Latigba na wa ni awon ara Ibadan ti nje oye won lai si ote tabi tembelekun.

Awon ara ilu Ibadan ti ni eto ifije oye lodo won. Ona meji ni nwon nje e. Owo ti Olubadan ati owo ti Balogun. Bi okan ba je, ekeji a si je.

Nigba gbogbo ni ero Radio tabi ero Gbohun-gbohun ma mbere wipe, bi Olubadan ba ku tani yio joye, ti a ko ri e a da lohun sugbon idahun ti a fi fun ni wipe bi Olubadan ba ku, Akinyele yio joye.

Igbintade Olubadan to salaisi je Otun Olubadan, lati ibe ni oye Olubadan ti kan a. Enikeni si ti mo wipe nigbati Igbintade ba ku oloye Balogun ilu li oye na tun tosi lati joye Olubadan.

Nitorina e jeki a fi ote sile, e fun Alade li ade, e fun Oloye li oye. Awa Eleti Qfe beri, a si fila, a se Kabiyesi fun Oloye I. B. Akinyele, Oke Ibadan yio gbe o si owo, yio si gbe o si omo. Ade a pe lori, bata yio pe lese Alaiyelnwa. Kabiyesi.


## Imoran Fun Eyin Abiyamo

Enyin abiyamo ewa ra 'Omorela' O dara pupo fun awon omode

A ma je ki omode ri orun sun daradara, o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma nba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo ogbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode.

**Omorela Baby Mixture**

SILE MEJI ABO (2/6d) FUN IGO KAN

wa lodo:

**Commercial Medicine Stores**

QUALIFIED CHEMIST

10, Victoria Street Lagos

## Polowo Qja Re Sinu Iwe Irohin Eleti Qfe




Eniti a nwo yi ni Qgbeni Dr. NNAMIDI AZIKIWE ti o nse Prime Minister ile apa Ila-Orun N. C. N. C. On li eniti o se ileri 7s 6d fun awon lebira jake jado ile Nigeria, sugbon koiti mu ileri re yi se.

## E Ko Ri Baiye Ti Nlo Tabi E Ko Ri Giri To Sojo

**Eko** Nigbati awon ojogbon ile aiye de oju site ti nwon si woye bi aiye na ti nlo, eyi ni ohun ti nwon je ak yesi.

Nigbati nwon ka iye awon enia ti o mbe lorile aiye ni odun 1931, awon omode kekere ti ko tayo omo odun mewa ni o poju nigbogbo aiye nigbana sugbon ni odun 1951 awon omo kekere ko ko nwonyi dinku jojo latigba na wa titi di oni yi, awon ko po ninu aiye mo.

Bakanna ni odun 1931 awon odomokunrin ati obinrin ti o je omodun 15 si 64 po gidigidi, sugbon latigba na wa ni nwon ti bere si dinku titi di odun 1951 ti nwon ko po nine aiye mo.

Sugbon 1931 awon arugbo ti o mbe li aiye nigbani, ko wopo sugbo lodun 1951 awon arugbo nwonyi ti wa po ju tobe ti o je wipe eyiti odun re kere ni ogota odun.

Nje enyin okewe wa, e ko ha ri bi aiye ti nlo, tabi e ko ri giri ti o ri sojo.?

## Ajele Agba Se Ikilo Fun Akinyo

**Ibadan** Lojo kini ana ni a gbo wipe awon ja ewe oye Olubadan le Akinyele enit o mbe lori oye Olubadan gegebi Balogun.

Siwaju ki ojo ifije oye na to, tot irohin ti kan kakiri wipe Ogbenkan ti a npe ni Akinyo nfe da rugu, du sile lojo na nitoriki awon ti aye je oye na,

Nigbati oyinbo Ajele agba gbo oro yi o lo funra re, lo ba Ogbeni Akinyo wipe, sora re, eso ni di owo re bi o ba le da ijogbon kan silo, kio mo wipe oro yio gbe o.

Irohin yi ni Ogbeni Adelabu gbo ti o fi te waya ofurufu si Gomina eniti o mbe lori itin re kakiri ile Yoruba wipe ko gbodo li owo ninu ifije oye Akinyele, a si gbo wipe waya na gun to opa kan. Sugbon Gomina ko ti le fesi nitori pe a ko ikilo fun mase wipe ki o ma se e.


## Enjoy Your Own Songs

SUNG BY YOUR OWN PEOPLE IN THE WAY YOU LOVE MASTERLY RENDERINGS OF TRADITIONAL AFRICAN MUSIC IS YOURS ...




OBTAINABLE FROM:

**The Association Of Nigeria Gramophone Dealers**

THROUGHOUT NIEGRIA

# Gba Eyi Fi Se Qgbon

Lati Qwo ESQ IKOYI

Eku atijo o, mo rope opo enia ni yio ti mase aferi wa idi re ni wipe aye ko si tobe ninu iwe wa, nitoripe ofu olupolowo oja ti gba aye pupo. Qgbon ologbon ni a fi nse ogbon, e gba eyiyi fi se qgbon, ogbon nbe li a npo li agbara.

Qpo ninu awon okunrin ti o ti nwa omo lati bi ti kori, beni nwon ni iyawo nile. Mo fe lati fi ye u y i n wipe ogidi leje awon obinrin aseko yi ni ko tun le bimo mo, sugbon bi obinrin ba ti mura, ti o ro dede, ti o gba dede, okunrin ko le fura si iru nkan bawonni.

Iwonyi ni awon obinrin ti ko le bimo
(1) Obinrin ti o je wipe nigbogbo igba ti o ba nse nkan osu re, aseko na a ma je akoko igbati osoma di aran-moju.
(2) Obinrin ti nkan osu re li orn ninu.
(3) Obinrin ti nkan osu re dudu.
(4) Obinrin ti o nri nkan osu re nigba meji, meta ninu osu kan.
(5) Obinrin ti ko nri nkan osu re pupo. Qpolopo iru nkan bi iru iwonyi ko njeki obinrin bimo.
(6) Obinrin ti ko se nkan osu mo.

Sugbon awon asiri ti a daruko nwon ko fi ara han fun gbogbo okunrin oko obinrin nikan soso li o le mo. Tiburuku tirere, bawo ni enia ti se le mo nipa iru awon obinrin ti ko le bimo mo l a r i n awon ti ko li oko.

Beni, bi okunrin ba mba iru awon obinrin bawonyi lo po, gbogbo obinrin ti okunrin na ba kolu yio ma di olokugbe, sugbon mo fe si nyin i eti, enyin. anfani ti o mbe lara obinrin ni wipe ki o bimo fun ni, nitori eyiyi na ni pataki ti a se nfe obinrin.

Qkunrin ti o ba n f e ni iyawo, ki o koko sakiyesi irin ese obinrin na. Bi obinrin ba nrin koja lo, ti eran e h i n ese re nmi jobo-jobo, ko si, bi Egbeji we ori fun oluwa re ko le bimo mo. Bi a ba si wadi lo sibi nkan osu re, o ni lati je okan ninu awon ohun ti a fi daruko, ao duro nihin na.

# Toko Taya Nja Si Qmo Kan Soso

**Apapa** Obinrin kan ti o bi qmobinrin kan fun qkunrin kan ni Apapa, afe ba qko miran rele si Ckeaywn, nitorina obinrin yi mu qmq ti o bi fun won li Apapa lo si ody Oyinbo ofetoju ilera ati alafia ilu lati gun abere fun ki oso lqwq oko

Awon Olof fo si o mo nipa oro yi g b a oro na lo so fun b a b a qmobinrin kekere na. Lojo ti uwqn fe lo wo oko nan, ni baba qmobinrin na wole de pelu ibinu, o ki qmq re mole o afe lati mu gbe lo. beni iya qmq na ba s gbe. gi wadi oko re, lati gba qmo na nitori ki baba re ma gbe lo, o ati gba iwe fun qmq na.

Iya qmq na bere si fa qmq na li ese baba re afa a ni ori. Bi ko ba si opolope oga kan ti o nsise ni Welfare Centre ti o ngbo ariwo ti o wole ba wqn, ese ni awqn iba fa qmo na ja si meji. Qga na gba qmo na kuro lqwq won o si fi si Juvenile Home.

MO NFE ESI LODQ ARA EKO ATI IJEBU

Gba mi laye lati se abere awonyi wipe, kini idi ti ti a fi npe dugbo kan ni Ybaleeda, Aaitautami, Idsamete lie Ipaiwo, ...
Qgba Kile fa a ti Ijebu ko fi nje Ojo?
Ifa wo ni awon fi fe Ijebu Ode?
Kini oruko Qba ti o koko je ni Ijebu Ode?
Tali o koko te ilu Ijebu.

Alufa Ojike




ILE YI LI AWQN AKEKQ NGBE NI ZARIA
(INSTITUTE OF ADMINISTRATION)

Ile, ti a ko daradara je apakan ilosiwaju ninu idagba-soke ile Hausa. Simenti oyinbo Burham se iranlowo gidi-gidi ninu kiko ile na, ati awon ile nla-nla miran kakiri apa Iwo Orun ile Afrika. Niwon adorin odun sehin, Simenti Burham ti se iranlowo li orisi-risi ona fun ilosiwaju ilu awonyi. Eyi yi fi han wipe, Simenti tire li o lagbara julo ti a si le gbekele ni gbogbo aiye.

BURHAM

PORTLAND CEMENT

BURHAM BRICK LIME AND CEMENT CO
BURHAM WORKS
TRADE
PORTLAND CEMENT
MARK
LONDON

## Irora Orikerike

Boya Kidinrin lo fa a.

Ise Kidinrin ni lati ma awon idoti ti o mbe ninu eje ara kuro nigbati ko ba si se daradara idoti na awojo po nibikan eyi lo nfa awon orike bere si dun ni.

Ohun ti a le fi wosan ni wipe ki a se itanlowo fun Kidinrin na ki o le se ise rere, Egbogi De Witts na kakiri siyo ni asi nla egbogi na n Opo iwe yi a ti ri gb. Iasi odo orisirisi eoia ti nwon nse iru ise ti De Witts se fun nwon. Danwo lera okan ni sobu egbogi.



Ohun to da wa loju ni wipe Egbogi DE WITT'S PILLS je eyi ti a se tonitoni, ohun elo re gbogbo lo si mo.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles




Eniti a nwo yi ni Ogbeni FESTOS OKOTIE-EBO ti o nse Minister of Labour okan ninu egbe N.C.N.C. on li o so wipe sile merin ojumo ni ijoba yio san fun lebira leko

## Ase Ti Ajele Fi Yan Akinyele Ni Olubadan

**Ibadan** Nigbati awon ijoye nlanla parapo ti nwon si yan Akinyele ni Olubadan, nwon mu lo sodo Ajele nitori lati fi ontele re gege Olubadan. Eyi ni oro ti Ajele na so siwaju ki o to fi ase si oye ti Akinyele je.

Ajele na so wipe ninu ofin ti o le fi joye tabi ti o le yo enia kuro lori oye ori keji ese kini so wipe nigbati ijoye kan ba ku tabi ti a da oye re duro, Gomina ni nikan soso loni ase lati yan olomiran dipo gegebi ase isedale ilu na ba ti lo. A si ti gbe agbara ase Gomina le emi Ajele agba lowo.

O si temi lorin wipe Ijoye I. B. Akinyele ti o nse Balogun Ibadan ni awon ijoye nlanla ilu yan dipo Igbitade Olubadan ti o salaisi. Nitorina pelu gbogbo agbara ti a gbe wo mi na, mofowo si, mo si fi otito te wipe I. B. Akinyele oloye Balogun Ibadan ni a fun ni oye Olubadan ilu Ibadan.

A si fi edo iwe yi Adele, Gomina Prime Minister, Awolowo Minister of Local Govt Rotimi Williams at Alaga igbimo nla ti Ibadan.



Eniti a nwo yi ni Ogbeni Awolowo ti o nse Prime Minister ile Ibon Orun A. G. On le sele ... [illegible] fun awon osise ti a si san ... yi se.

## Awon Iyawo Olopa Ma Kuro Ni Bareke

**Obalende**, Irohin ta si wa leti wipe awon Olopa nfi se ofin kan lati ... awon obinrin ti o mbe ni Bareke Obalende ku.

Gbogbo awon ki gbogbo ni ... obinrin kansoso Obinrin o wa nibe ni wipe awon obinrin ... awon ba le won kuro lodo ... nibo ni nwon o ma gbe tabi ... kini o rope awon o se jeun, ti ... koiti si ... ba won sile.


NOW,
**AVAILABLE**

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS DISTEMPERS,
SAFES Etc.
Just write, Call, or
Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**

20/28, Balogun Street,
(P. O. Box 395) Lagos,
AND
NEW COURT ROAD
IBADAN


## Oye Olubadan Fe Da Rukerudo Sile Ni Ibadan

**Ibadan** Lehin iku Igbitade Olubadan, gbogbo awon agba ijoye nila Ibadan fi ohun sokan lati fi oloye Akinyele ti o nse Balogun Ibadan je oye Olubadan nitori lati ti egan on ni oye na te si. Lehin ti nwon ti yan Akinyele gegebi Olubadan tan nwon lo fi han Oyinbo Ajele, nwon gbaa gegebi Olubadan.

Si iyalenu gbogbo enia awon egbe kan yan oloye Bello Akinyola ti o nse Osi Balogun je oye Olubadan awon si mu lo sodo Oyinbo Ajele sugbon Oyinbo na so wipe on so wipe on ko nmo oko omo ki on tun mo ale re. Awon ijoye ti mu Akinyele wa siwaju on gegebi Olubadan on si, ti fi otito te e:

Nigbati nwon adari pada lo wa sile ni rogbodiyan fe be sile, enia merin fi ara sese moto kan si baje kan le. Awon agba ijoye ti o yan Akinyele ni Olubadan ni Salawu Aminu. Yusufu Kobiowu, Akinwale, Olugbade, Iresin, Oloye Iyalode



Eniti a nwo yi ni Ogbeni Towe Enahoro ti o nse Minister of Home Affairs, okan ninu egbe A. G. On ni enili o da moran fun ijoba wipe ki awon jesi owo ise Lebira je sile marun lojumo.

## Nofiu Disu Dologbe

EBUTE METTA Gbuke ni a gburo iku oga Kapitala ti Lagos Town Council ti Ebute meta, ti a npe ni Nofiu Akanni Disu ti ile re mbe ni Ololo Street.

Ologbe yi ku ni eni ogoji odun, o fi iyawo meta ati omo mefa sile aiye lo.

Omo Oloku Sule majerahun ati Ogbeni Asani Majerahun.


WEST REGIONAL PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD

VACANCIES.

The Western Regional Production Board has vacancies in its Accounts Section fo the following posts:-

(a) Senior Accounting Assistant
Salary Scale : £510 x 30 - 690;

(b) Accounting Assistants Grade II
Salary Scale : £318 x 18 - 360;

(c) (Accounts Clerks Grade I. Salary Scale:
£195x15-£300;
( " " Grade II. Salary Scale:
£132x12-£180.

The posts are not pensionable but successful candidates will be required to conribute 10o/o of salary to the Provident Fund Scheme to which the Board contributes an equal amount and interest is payable on the whole at the rate of 2½o/o per annum. Other conditions of service are similar to those obtaining under Government.

Application in the applicant's own hand-writing together with full details of experience and qualification should be submitted to the Secretary, Western Regional Production Development Board, Ibadan, not later than 26th of February.

## Iye Enia To Mbe Lorile Aiye

**Eko** N'no odun 1950 nigbati a se idiro gbogbo awon enia ti o mbe li orile aiye, iye enia ti okunrin ti o mbe ni gbogbo aiye je 486,000,000. Iye awon obinrin to mbe lori'le aiye je 275,000,000.

O si tun se ni odun 1955, ti a tun ka gbogbo enia orile aiye, en'a ti tunbo po si, iye gbogbo okunrin sebaiye 537,000,000. Iye awon obinrin to mbe lorile aiye je 333,000,000.

Enia ko tire po ni aiye mo ni odun 1921 ti nwon ka iye enia ti o mbe ni orile aiye okunrin je 539,000,000, iye awon obinrin je 400,000,000.

## Gomina Yio Fi Oku ta Titun Lele



IBADAN— Oloja Gomina tile Yoruba Sir John Rankine yio fi okuta le ighimo titun ile nitu Ibadan ijo 1st March 1955.

## Afoju Kan Fi Owo Mu Ekute

EKO— Afoju alagbe kan ti o joko ti nse agbe ebun ti yio je ni ekute kan ti awon omode keke ti nla kakiri li o ko wo inu apo yokoto okunrin afoju na.

Okunrin afoju na sakiyesi wipe ebun kan oja wuke-wuke si apo on ati ariwo ti awon omode npa, o rope owo je uda kan li o to wo ho apo on, o mu ekute o mu lwo apo re.

O si nkigbe wipe kai, kai, Barawo, kai barawo o ki apo re mole lati fi na omo jaguda ti o mu owo re dani ninu aon, lainy o lo fi igi na afoju miran ti o mbe ni ijeko pelu.

Gbogbo awon afoju gbija, awon si bere si na ara won li opa.

Eyiti ekute ko s'nu apo re ko ye igbe ke wipe kai, ka barawo,

## Qmode Kan Ta Okuta Lu Opindan

**Eku** O natio Opidan kan ere nian ile ebe Onigno(Forester) okunrin onidan na ni ki nwon yin ibon lu on. Nwon y nbon lu ko si ku. O je iyalenu fun opo enia.

Lojo keji bi okunrin opidan na ti nsoja lo ni Olowogbowo, omode ilewe kan ti o ba Laba ti lo woran opidan na li ana ri i, o si ta okuta ba okunrin na li egoit.

Jon bi Opindan na o le omo a ba, o e mu, o bere wipe kini mu fi se e. Omo na dahun wipe nigbati nwon yinbon si o lanu ka ba o bawo ni okuta kekere se ba o. Erin pa a, o si fi sile

## Kili Onigbagbo Ti Ro Eyi Si

Opolopo awo Onigbagbo li o npe mi nija, ija mi na ya lowl. N nu wo Johanu 5. 31. Jesu so wipe bi emi ba jeri ara mi, nje asao li eri mi.

Johanu 8, 14 bi emi tile jeri ara mi, otito li oro mi, eyi ko ha ledi si ara won bi?

Isaiah 45. 23 Olorun so wipe gbogbo eunkun ni yio wolę fun on gbogbo ahon ni yio si bura, sugbon Mati 5. 34 so wipe lotito, lotito ni mo wifun nyin ki enikeni mase bura,

3. Awon oba keji 8.26 so wipe omo odun mejilelogun ni Ahaziah nigbati o joba. Kronika keji 22,2 tun so wipe omo odun mejilelagoji ni Ahaziah nigbati o joba,

Bayi ni gbogbo oro ninu iwe Bibeli ko ba ara won mu, Sugbon ko si enti o le so tabi ki o jeri wipe oro inu Alukurani tako ara won bayi. Mo si rope awon onigbagbo yio gba wipe mo to Lemomu sitoto.




A GIFT FROM HEAVEN!

BAMWO BABY MIXTURE

OF EXCEPTIONAL VALUE IN PREVENTING SICKNESS, CURING FEVERS, COUGHS, MEASLES AND TEETHING AILMENTS. ENSURES SOUND SLEEP.

PRICE 2/6 POSTAGE 1/-

THE EGBA TRADING ARADAN STORES, 44 DENTON STREET, P.O. BOX 2, EBUTE METTA & BRANCHES


## CLASSIFIED ADVERTISMENT


"Be Successful," Sturdy at home, Sparetime. The English Association of Accountants and Auditors, or The English Association of Secretaries Examination, Exemptions Considered.

London College of Accountancy & Secretaryship

9 Charles Street, Newport MON ENGLAND.


## Olowogbowo Area Council

There will be a general meeting of Olowogbowo Area Council Division II on Sunday 20, 2, 55 by 11 a.m at the Rialto Cinima Lagos As matter of importance will be discussed all members are cordially invited.

THE FAULTY DRIVER






REDIFFUSION

LISTENERS

ENJOY
DAILY
INTEREST AND ENTERTAINMENT
FROM 6 A.M TILL 11 P.M
UNRIVALLED
SERVICE ALREADY
INSTALLED IN
ONLY 2 YEARS IN NEARLY 40,000
NIGERIAN WESTERN REGION HOMES


Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370